“Ẹsin ìmọ̀ràn ni

Lati ọdọ baba Ruqọyyah Tameem ọmọ Aosi Addariyy kí Ọlọhun yọnu sí dájú dájú anọbi kí Ikẹ Ọlọhun àti ọlá Rẹ má bà sọ pé: “Ẹsin ìmọ̀ràn ni”, a sọ pé: Fún tani? O sọ pe: “Fún Ọlọhun, ati fun tira Rẹ̀, ati fun ojisẹ Rẹ, ati fun awọn aṣiwaju Mùsùlùmí ati apapọ wọn”.
[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n sọ pe ẹsin duro lori imọkanga ati ododo, titi ti eeyan fi maa pé e gẹ́gẹ́ bi Ọlọhun ṣe ṣe e ni dandan, ni pípé láìsí ikudiẹ-kaato nibẹ tabi irẹjẹ. Wọn wa sọ fun Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- pé: Ìmọ̀ràn fun tani? O sọ pe: Akọkọ: mímọ fun Ọlọhun ti ọla Rẹ ga: Pẹ̀lú mimọ iṣẹ kangá fun Un, ati ki èèyàn ma da orogun pọ̀ mọ́ Ọn, ki a si gbagbọ ninu iję Oluwa Rẹ, ati ìní-ẹ̀tọ́ si ìjọsìn Rẹ, ati awọn orúkọ Rẹ ati awọn ìròyìn Rẹ, ati gbigbe ọ̀rọ̀ Rẹ tobi, ati ipepe lọ sibi ìní ìgbàgbọ́ si I. Ẹkeji: Ṣíṣe mimọ sí ọrọ rẹ òun náà ni Al-qur'aani alapọnle: pẹlu pé kí a ní adisọkan pé ọrọ ọrọ rẹ ni , àti pe oun ni igbẹyin awan tira rẹ, àti pe oun ni o se iparẹ gbgbo awan ìlànà òfin tí o tí wa síwájú re6, kí o sí máa gbé tóbi, kí o sí máa kàà bode yẹ koro ka , kí o sí máa lo èyí tí ìdájọ rẹ fojú hàn, kí o sí gbafa fún èyí tí o jọra wàn tàbí èyí tí o ru'ju nínú rẹ, kí a sí jìnà sí ituku awan tí wan tú ni itukutu, kí a sí máa ni iwoye sí awan ìkìlọ tàbí isiti rẹ, kí a sí má tán awan imọ rẹ ka , kí a sí pepe sí ará rẹ. Ìkẹta: Ìmọ̀ràn fun ojisẹ Rẹ tii ṣe Muhammad- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a-: Pẹ̀lú ki a ni adisọkan pe oun ni igbẹyin àwọn ojisẹ, ki a si gba a lododo nibi nǹkan ti o mu wa, ki a si tẹle àṣẹ rẹ, ki a si jinna si ohun ti o bá kọ̀. Ki a si ma jọ́sìn fun Ọlọhun àyàfi pẹ̀lú nǹkan ti o mu wa, ki a si maa gbe iwọ̀ rẹ tobi, ki a si maa pọn ọn le, ki a si maa tan ipepe rẹ ká, ki a si maa fọn ofin rẹ ka, ki a si maa tako àwọn ẹ̀sùn ti wọn ba fi kan an. Ikẹrin: Ìmọ̀ràn fun awọn aṣiwaju àwọn mùsùlùmí: Pẹ̀lú riran wọn lọ́wọ́ lórí òdodo, ki eeyan ma si du àlámọ̀rí naa mọ́ wọn lọ́wọ́, ki èèyàn si maa tẹti ki èèyàn si maa tẹle àṣẹ wọn nibi itẹle ti Ọlọhun. Ikarun-un: Ìmọ̀ràn fun awọn Mùsùlùmí: Pẹ̀lú ṣíṣe dáadáa si wọn ati pípè wọn, ati ki èèyàn má fi suta kan wọn, ati inifẹẹ oore fun wọn, ati kikun wọn lọ́wọ́ lori dáadáa ati ìpayà.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/66516